The Chief Secretary to the Govern…

# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL. I. No. 45. SATURDAY, MAY 19, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor :*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Onisọwo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orịṣirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orịṣirịṣi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi ṣi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. I. M. Johnson,**
9, Seale Square,
Phone 227 Lagos.
P.O. Box 498.



## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işe ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po 9.



## ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.



## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Sabu rẹ ni No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aşọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyo, Yomini, (*Satten*.)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.



WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.



KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AŞỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to şeşẹ de fun u pẹlu awọn MAŞINI iranşọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mäse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

### KERE O! KERE O!!

*Tuesday* to mbọ (ọjọ mẹrin oni) la fi Asọye ti awọn Ẹni-nla wa na si ni ọjọ 22 oṣu yi ni Ile Iwe Ijọ Onidunkun Oyinbo (*St. Paul's Breadfruit School-room*) ni agogo meje abọ (*7.30 p.m.*) lalẹ. Ọgọrọ ni awọn to ti ra *Ticket* tiwọn pẹlu Iwe Orin ti a wi.

Ọrẹ, tete wa ra tirẹ bi bẹkọ ọbọlẹ yio ki ọ!!!

### KUDẸHINB[illegible]O KO DAGBERE.

A ba Eṣugbayi [illegible]ko ọmọ-alade ati awọn iyekan rẹ to ku kẹdun iku ẹgbọn wọn Kudẹhinbu Ọmọ-Ọba to ṣẹlẹ ni Isalẹ Eko ni *Tuesday* ọsẹ to kọja a si sin si Ikoyi.

A gbọ pe Ọgbẹni yi ni Ẹgbọn gbogbo awọn Ọmọ Dosunmu Ọba.

### AIYE IJỌ'UN KO JỌ TI SẸYI.

Awọn Ọgbẹni Samuel Ayọdele Ọwesi Macauley, J. Ade: Craig, ati Okunade Akibayọ nmura Ilu Oyinbo fun ati lọ kọ iṣẹ *Doctor*. bẹ si ni Ọgbẹni Thomas Ẹkundayọ Williams aburo Ọgbẹni Labọde Williams awọn ọmọ Z.A. nmura lati lọ bakanna fun iṣẹ *Lawyer*; a gbọ pe ọkọ Abinsi Ayara-bi-aṣa ni nwọn yio ba lọ ni ọjọ 25 oṣu yi. Eyi wun wa o.

### GBERE, ỌMỌ, LIṢABI!

A dupẹ Iwe irohin Ijọ *Church* Alagogo *Christ Church* (*Catheldral*) *Magazine* ti Ẹni-ọwọ M. S. Cole Alufa Ijọ na bẹrẹ si ṣe loṣoṣu ti o fi ṣọwọ si wa lọsẹ yi. Irohin to mbẹ nibẹ jẹ iṣiri lọpọlọpọ gẹgẹ bi iṣẹ Ijọ na ti nlọ si. Ọwọ a r'oke o.

### ỌKU, ỌMỌ ALARẸ.

Bẹ si ni A dupẹ Iwe Irohin oṣoṣu ti Iṣẹ *Nigerian Labour Bulletin* ti Ọgbẹni J. A. Oluṣọla fi ṣọwọ si wa pẹlu; Ọgbẹni yi jẹ Oniwe Irohin na ọrọ iṣẹ to sọ sibẹ si yayi. Ede Gẹsi ni a fi kọ awọn Iwe Irohin mejeji nwọnyi, a nta wọn ni sisi-sisi.

### ORI KO MỌ IBUSUN!

A ba T. Hutton-Mills Ọlọla, Baba Ẹgbẹ *Congress* kẹdun gidigidi fun iku aya rẹ Florence to ṣẹlẹ ninu Ọkọ *Appam* ni ọjọ 22 oṣu to kọja nigbati on ati Ọkọ rẹ nlọ si Ilu Oyinbo gẹgẹ bi a ti ri ka ninu Iwe Irohin Ilu Agayin kan ti a npe ni *Gold Coast Independent*. Ara Iya-afin na ko ti da fun sā kan.

### ARA FẸ JOJO, ARA FẸ ISINMI LẸKỌKAN.

Ọgbẹni Duro Thomas Oniṣowo-Towolawi ti 55 Ita Mase gbatẹgun lọ si *Calabar Bonny Port-Har-Court* ati *Cameroon* ninu ọkọ *Zaria* to lọ nibi ninu *Monday* ọsẹ yi, yio si pada bọ wale niwọn ọsẹ meji. Ọkọ a re fo o.

### KARAOLE, ỌRUN 'RE.

A ba Ọgbẹni Abọyade Cole ati Iya-afin Titilọla Cole ati awọn ẹbi to ku kẹdun iku baba wọn Charles Collins Cole to ṣẹlẹ ni opopo nla ni *Saturday* to kọja.

### ẸKUNDAYỌ, KU RỌJU.

Gudugbẹ ja ni alẹ *Monday* ọsẹ yi ni Ita Ajẹlẹ ati Ita *Campbell* nigbati a gbọ iku Aya Ọgbẹni T. K. E. Phillips Aluduru ti *Church* Alagogo Ọmọ *Bishop* ati Mrs. Oluwọle.

Kiro kifọ ni Iya-afin yi; A, oṣe! oṣe!! O fi Baba, Iya, Ọkọ, Ọmọ, Aburo ati awọn iyekan rẹ silẹ, O si ṣanlọ bi ẹiyẹ? *Hun, hun, hun, hun*, !!!

Ọgbẹni Phillips, maṣe banujẹ pupọ gẹgẹ bi awọn ẹlomiran ti ko ni ireti.

### FỌLAṢADE WỌ INU OGO.

A ba *Bishop* A. W. Howells ati awọn iyekan rẹ kẹdun iku Aburo wọn Iya-afin Fọlaṣade Howells to ṣẹlẹ ni Abẹokuta ni lọlọyi; ki Oluwa dẹl[illegible] u.

### A DUPẸ, IJA IMALE PARI.

Ọgbẹni Ijalẹ tun bẹrẹ si nkan ti nwọn nṣe lọdọdun, ti nwọn nmura bi jagunjagun lati lọ ro Mosalasi Ọdun fun Irun ọdun kekere: ẹnikan gbe kotopo ru, ẹlomiran gbe ere, Ọgbẹni papa wa lehin, lori Ẹṣin: gbogbo awọn to ba lọ ṣiṣẹ na lo mu ada dani.

### ASỌ-SILẸ LO NJE ỌRỌ ANA.

A fi ọrọ Ọgbẹni Oludemi di igba miran.

### ṢIỌ! ALAI LOJUTI, ALAI NI FIRE!!

Adajọ kekere Ẹni-Ijuba M. C. Greene ju Albert Forever Coker s'ẹwọn Oṣu mẹsan pẹlu iṣẹ-aṣegan ni *Wednesday* ọsẹ yi fun ẹbi ti Kotu da a pe o lọ gbowoje lọwọ Alufa Aguda Father Woodley ẹniti o purọ fun pe ki o fun on ni £1. 19. 3. lati fi gba ago ti awọn ọmọ Adiẹ wa, ti o ni o de fun Alufa yi: bẹ si ni o lọ gbowo lọwọ Alufa H. A. Lewis, ti *Church* awọn Oyinbo l'ọdan, to si purọ fun u bakanna.

A tun gbọ pe ọkunrin yi lọ si Ibadan laipẹ o si ni ki awọn Imale ibẹ wẹ on ni wo-nka, a si sọpe nwọn ṣe bẹ ati pe Salami ni Suna ti nwọn fun u: a gbọ pe ọkunrin yi wipe on wa ri pe Isin Igbagbọ ti on wa ko gbe on, nitorina ni on ṣe lọ pa isin da!!!

### ẸJỌ CHURCH NI GANRAN.

A fi Ẹjọ larin Ijọ *C. M. S.* ati Ijọ *Africa* Ọmọ Ibilẹ si Ọtunla ni agogo mẹsan arọ.

Orukọ awọn *Lawyer* ti *C. M. S.* ni
Eric. O. Moore Ọlọla (Aṣaju)
E. J. Alex Taylor Esq.
J. T. Nelson Cole (Alaka) Esq.
M. A. Akiṣemọyin Esq.

Ti Ijọ A.C. ni
Ọgbẹni J. Egerton Shyngle, *Lawyer* Jiga.
Niwaju Adajọ Sir F. A. Vander Meulen ni a nro Ẹjọ na.

### BAYI LỌRỌ RI.

A gbọ pe Ẹwọn Ọdun mẹwa ni Oyinbo Adajọ Igberiko Ijẹbu-Ode ju Kadiri Jagun ọkunrin ti o jẹbi rirọ-owo fadaka si, kiṣe Ẹwọn Ọdun mẹtalelogun gẹgẹbi Iwe-Irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi ti wi, ninu "Irohin-ṣoki." Awọn ti nwọn wa nidi Iwe ninu Iṣẹ-Ọba lo sọ eyi fun ni.

---

### ẸKỌ FUN AWA ỌDỌMỌDE IMALE EKO.

Awọn Obi to foju ko fẹ ki awọn ọmọ wọn foju; biti awọn Imọle kọ.

Ẹkọ yi wa fun gbogbo awa ọmọ Imale to ni ori lati ro, ti o si nṣe akiyesi bi gbogbo nkan ti nlọ si ni aiye, ti o sin ti jadi ọpọlọpọ irọ ti awọn oniwasu ti pa fun wa lati le ri owo gba lọwọ wa, eyiti ko jọ gbogbo wa loju mọ nisinsinyi, irufẹ awọn irọ bai ti sọ gbogbo ioi Iwasu Imale di ibi ariwo bi Oja Ita Faji.

Ẹkọ yi ko jẹ pataki fun awọn ẹlẹgbẹ wa, arisẹmaṣe, alugo kiri tabi awọn alamupara ọti, tabi awọn ti obinrin Ile wón rin kiri bi aguntan, tabi ti wọn kobikita fun ọmọ ti wọn bi fun wọn, lati fun ni ẹkọ.

Agbọ pe oto adọrin ọdun tabi jubẹlọ ti Isin Imale ti wọ Ilu Eko, ati pe oto ogoji ọdun ti awọn Imale Eko ti pin si meji, awọn agbalagba gbana gẹgẹbi oye ta ri larin pupọ ninu awọn agba Imale Isinsinyi, odabi ẹnipe, awọn jẹ ẹniti okan gba Isin to si nfi Ọja weri lasan ki a le mọ wọn ni Imale, ti o si nlọ si Mọṣalaṣi lọ jẹnu wuyẹ wuyẹ laimọ kewu kan ko sin fi ori balẹ, nitoripe wọn ko wadi Isin rara bi awọn ọmọde isinsinyi, bẹni awọn alufa igbana ko sin fi idi Isin han wọn. Otilẹ jẹ ibẹru lati wadi Isin jinlẹ lọwọ awọn alufa igbana. Ṣugbọn awọn aluta igbana ri nkan gbajẹ lọwọ awọn ope wonyi. Pupọ igba laripe bi ọdun Imale ba de, awọn tojẹ ogbologbo abọriṣa to ni owo lọwọ, wọn awe lawani wọn a sin ta mọ Ẹṣin o di ọdun ni yẹn. Wọn ṣe eyi bai loju mi titi di ọdun 1887. Aṣọ dudu ni wọn fi bo Isin loju nigbana. Ṣugbọn nigbati otẹ ilu ti bẹrẹ sile lati 1915, ni Aṣọ dudu ti wọn fi bo Isin loju ti faya. Ṣugbọn sibẹsibẹ lati ẹnu oṣu mẹjọ wa yi, wọn tun fẹbẹrẹ si fi aṣọ dudu bo Isin lori, eyiti omu jamba nlanla ba awọn enia wa tojẹ pataki ni ilu ti awọn oyinbo oloye nlanla larin ilu bu ọwọ fun. O tọ ki gbogbo Imale mọdaju pe ilaju ti bọ si arin Isin, ko sin yẹ ki wọn di Ilaju lọwọ. Messrs Ipayẹ & Bros. ti sọ asọtẹlẹ yi fun gbogbo awa Imọle ninu iwe Almanack rẹ ti ọdun 1922-1923. Ẹniti ko ba gba, on lomọ. Ẹkọ ti afẹ lati fikọni nipe, otọ ki gbogbo awa ọmọde

Imọle fi ere şişe silẹ, ka sin foju si Ilaju to wa niwaju wa yi, kalẹ mọ ọna ti awa yio gba, nitori gbangba di Ẹkun kedere bẹwo.

Nisinsinyi awọn Ijọ Imale orişi mẹta lo wa ni Eko, şugbọn ninu awọn Ijọ mẹta yi, ijọ Imam Dabiri nikan laripe onlọ siwaju nipa ọlaju, ọna Ẹsin wọn yanju ko sin fi tabitabi si enia lọkan lai si aroye, won ko şe awun lati na owo wọn lati kọ awọn omọ wọn ni ede larubawa ati ede Igẹsi pẹlu, wọn sin kọ awọn obinrin wọn ni ede larubawa ti wọn fi kirun pẹlu itumọ rẹ ni ede Yoruba. Gbogbo awọn omọ Ile iwe wọn, lomọ Fatiya titi de Alamutarakefa si ede Yoruba. Gbogbo obinrin wọn mọ itumọ bakanna, eyi tanbọ mu awọn obinrin won lara lati ma kirun dada, nitori wọn mọ itumọ nkan ti nwọn nwi bi wọn ba nkirun. A sin gbọ nisinsinyi pe meji tabi mẹta ninu awọn obinrin to wa labẹ Ijọ Imam Dabiri fẹbẹrẹ si lati fi Alkoran şe wasi fun awa ara Eko, nigbati o jẹpe awọn obinrin ti wa komọ ju iwa şina ati Ijo lọ, bẹni ẹnyin alufa nsọ fun wa pe Ijọ Dabiri kodara, eyi ma to ero fun ẹniti omoye. Awo ya tabi koya ? Bi awo ba ya bi oya, ẹlọwo Alufa Yesufu Kekere ẹniti ko ju ẹni ọdun mẹrin-dinlogun lọ lojude Ọrẹ Ọfẹrọ ni Okoawo, bi o ti nyi igbi kewu lu awọn alufa oni lawani nlanla ti otikewu lati igba ogun nami nalẹ, ti ko mọ itumọ Alimmudu. O le ni ẹgbẹgbẹrun ọna mẹrin enia tó wa nibẹ.

Boşe igba lailai ni afẹku atiba, şugbon Ilaju kojẹ ki irufẹ iwa aimọ Ọlọrun bẹ wa ni Eko mọ. Kinişe ti Ẹnyin Alufa ti Eko kọ wa ni itumọ kewu ti ẹko wa lati ibẹrẹ wa, gẹgẹbi ti Ijọ Imam Dabiri ?

Nipa ka ke Alkoran tan (Saki) laimọ itumọ, kasin gbemi gun ori Ẹşin (Wolimọ) ki wọn ma pariwo tẹle ni lẹhin bai pe ' Elekuru gbọn yẹyẹ ! Elekuru gbọn yẹyẹ ! lori gbogbo eyi ki ẹniti aşe wolimọ fun ko ma le sọ itumọ Esu Kewu kan delẹ, ki alufa sin sun Iya ati Baba ọmọ na nawo bi £60 tabi jubẹlọ lairo tẹlẹ, ojẹ nkan ti ko dara. Mo sin gbagbọ pe bi awọn alufa ba gba iya ọmọ ati baba ọmoyi ni amọran ni, wọn kole na £60 yi tan sori ọmọde yi ko to mọ gbogbo itumo Alkoran tan si ede yoruba. Nipa bai ọmọde yi ko ba mọ ofin Ọlọrun lamọ ye, ko ba sin mọ iwa to tọ lati husi baba ati iya rẹ, jupe ki oma sọro aida si wọn lọ, ko sin ma lu Igo kiri lẹhin to ba ti muti inu rẹ tan.

Mo mọdajudaju pe ọna Ilaju ti Alufa Dabiri gbayi, yio şe anfani pupọ fun awọn ti ko fẹ lati fi ọna itanjẹ (aimọ on ti wọn wi) sin Ọlọrun, şugbọn alufa yio korira rẹ nitoripe o se ọna jijẹ fun awọn arişẹmaşe alufa. Şugbọn mọ daju pe yio ye gbogbo wa bi aba ronu. Bi o ba jẹpe gbogbo awọn to lọ si ilu Mẹka panu pọ, wọn sin mu ọna Ilaju bai wa, ako ba ma dupẹ lọwọ wọn lailai gẹgẹbi ikan ninu awọn Alaji ti şe awọn obinrin wa lore, to daşa buba silẹ fun awọn obinrin lati bo igba aya wọn. Oluwa ko bukun Alaji na. Gbogbo awọn akọni ni kewu ma kọni ni itumọ, wọn kole fẹran Imam Olaju ; Awọn agbalagba fọju si ọna na, şugbọn ẹnyin ọdọmọde ẹmajẹ ki oju fọ, ẹlọ kewu pẹlu itumọ bi bẹkọ, ẹlo akoko nyin danu lasan ni. Bi iwọ bade ibiti Yesufu nşe wasu ni Oko awo, wari pe ilẹgbelẹmi fun awọn alufa ti o ti fi kewu şe fari fun awa ope. Ẹmajẹ ki aşọ dudu bo nyin loju mọ, oju ti la pupọ larin awa imale ati onigbagbọ pẹlu.

AWO YA TABI KO YA ? AWO YA !

AJILARAN.

## Fashionable Wedding

AT ST. PAUL'S.

Our next issue will contain, *inter alia*, a Pen-picture of the Marriage solemnized between Miss. Oyinkan Ọla'oşebikan only child of The Hon : and Mrs. Kitoyi Ajasa and Mr. Morounfolu Abayọmi a Legal Practitioner of this colony, on Thursday last in St. Paul's.

When we say that no less than Ten Clergymen of The Anglican Connexion take part in the solemnization, we leave our readers to form an idea of the Class in which the Wedding is placed.

[ED.—E. A.]

Ati nşe ireti lati igba ti a ti kọ iwe si Igbimọ Ilu (*Town Council*) nipa ti potọpọto ti nşan ni Ita Onikoyi (Onikoyi Street) ni ẹba Idunşagbe, a ko ri ohun kan ti awọn Igbimọ wa wonyi şe. Papa ẹnikẹni to ba nrin si adugbo ti a da oruko rẹ yi yio ri eri ati orun buburu ti o le jẹ ipalara fun wọn ati awọn aladugbo ibẹ na.

A tun fe ki awọn Igbimọ ilu yi lọ wo adugbo yi, nitoripe oto akoko ti o yẹ ki a la oju agbara (*Gutter*) silẹ. A ko le şe alai ma dupẹ fun awọn Igbimọ ilu wọnyi fun oniruru atunşe ti nwọn ti nşe ni lọlọ yi, a ni ireti pe Ogboni wa, Mr. Webb, Adọgba-jalẹ-ọkunrin ki yio fi oju fo ibere wa yi ni akoko yi.

Atunşe di ọwọ nyin o.

AKIRIMANU.

## THANKS FOR SYMPATHY.

Messrs. M. A. Ọdunjọ and S. A. Ọyadina hereby return their sincere thanks to all those who either by personal calls Letters or Telegrams have expressed sympathy with them on the death of their Uncle Mr. Disu Ọdẹdina Adetutu who departed this life on the 7th instant.

**EKO AKETE:**

EKO, SATURDAY, MAY 19, 1923.

## IJA IMALE TAN, RIKIṢI PIN, ALAYỌNUSỌ, TIRẸ TI JẸ?

Tayọtayọ ni a fi gbọ ni ọjọ Jimọ (*Friday*) ọsẹ to kọja pe Ija Imale, eyiti o ti nja ranyin larin wa nibi lati ọdun keje wa (1916) jaja pari: a si gbọ ti ayan ti Alaji Salusi ti Lafiaji ṣe pẹlu awọn Janma toku ki ọrọ na to le lori, tobẹ ti a fi sọ pe ọtun tu-nba fun osi, osi si tu-nba fun ọtun, ti gbogbo rẹ si ṣe weku bi ẹni so ọgọji mọ ọgọjọ.

Nisisiyi ti a ṣẹ ri pe iwa jagidi-jagan ati asọ gbogbo ṣẹ nka 'sẹ, o ku si ọwọ awọn ẹlomiran ti o jẹ pe iṣẹ ayinsi ni nwọn mọ ṣe, ki nwọn lọ wa ọkọ wọn si 'tọ ki nwọn si lẹ gasi wọn bọ awọ pẹlu: irufẹ awọn ẹni bayi mọ ara wọn, nitoripe onjẹ ifa ti awọn nri jẹ ninu didaru-ilu ko kere: bẹ ha kọ ni awọn kan tun nsọ kiri ni lọlọyi, pe Adele Ọba Sir Donald Cameron ko fẹ ri imi Ọgbẹni Oloye Oni-fila-funfun kan ni atan? pe nṣe ni Ijọba tilẹ se Oloye na mọ ile? ati isọkusọ miran:

Ẹnyin ara-ilu, niwọn igbati a ko ba ye so irun iwaju pọ mọ ti ipakọ bayi, isimi ko mai ti si: irufẹ awọn enia wọnyi ni nwọn nfẹ sisin ku ti nwọn nfi ọwọ ra imu: nigbana ko ni ṣai di ọrọ "Adiẹ ba l'okun, ara o rokun, ara o r' adiẹ." Ṣugbọn gẹgẹ bi a ti nsọ ninu Iwe-Irohin yi lati ẹhin wa, nigbakugba ti ẹ ba ngbọ iru ọrọ mọṣaṣi bayi, eru eke ni ki ẹ ma ku le awọn ẹni bẹ lori, nipa bayi, a o le fi ẹdọ le ori ororo.

A ko le ṣẹṣẹ tun ma tọ pinpin ọgọrọ owo ti awọn elomiran ninu awọn Imale ara wa ti na danu latari asan lati igbati Ija wọnyi ti bẹ silẹ: ẹlomiran gidi koi ti bọ ninu igbese to lọ da si ara rẹ lọrun ni apapa-ndodo pe ki oju maṣe ti on fun ọlẹ ti tọtun-tosi wọn jọ nṣe bayi. Ṣugbọn a dupẹ a tun ọpẹ da pe gbogbo eyi yio jẹ ẹkọ iyebiye fun irufẹ awọn ẹni bẹ nijọmiran pe owo-kope ni Ija-ajaku-doro-gbo.

Ẹnyin Musulumi Eko, a kan sara si nyin o, a si ro pe iru ifẹ to ti wa larin Kiriyo ati Alagbada ṣaju Ija yi, yio tun sọji lẹkan si, tobẹ ti ko ni si ẹmi "A di-karewa" mọ larin wa: o si jẹ ohun to dun mọ ni pe ni diẹ lẹrẹ, ki Awẹ pari la gbọ ipari ti Ija na. Eyi fihan gba-ngba pe laisi-ani-ani, Maleka ti ṣe *Amin* si Iwa-isẹra -ẹni nyin, nipa Awẹ gbigba lọdunni ju ti atẹhinwa lọ.

Barika ọdun, Ẹ ku Iyedun, Ki Ọlọrun mu ni di ẹmiran.

*Asalaama-laikum!!!*

## ALL HAIL, VICTORIA DAY!!!

BY THE EDITOR.

Throughout our school days we were wont to observe every 24th May as *Queen's Birth-day*, but a few years since the demise of *Her Majesty*, a commendable but inappropriate step was taken by *Lord Meath* in *England* which resulted in the change of the above to *Empire Day*.

At first, the alteration may appeal to many, having regard to the fact that during the unprecedented, prosperous and long reign of the Saintly Queen, British Empire has a unique history with reference to her wonderful developments politically religiously, commercially and territorially: this must have operated in the mind of the noble Lord before effect was given to the change.

But we are strongly of the opinion, that greater service could have been rendered to millions of school children of the present day throughout the Empire, were the all-enlightening name Victoria Day retained, because the happy reminiscences with which the Great name is associated from time immemorial are easily recalled to mind; it is the undying name of the Good Queen, in whose reign we in this part, to say nothing of our other fellow-loyal subjects beyond the seas, are brought in closer contact with the Mother Country

We pass this suggestion to the "powers that be" for their information and action.

God save the King.

(In our next issue, we propose publishing fev speeches made by His Excellency, Sir Alfre Moloney, K.C.M.G., Messrs J. S. Leigh, J. Bucknor and His Honour, J. Smallman Smi at the State Banquet given at Government Hou during the celebration at Lagos of The Quee" Jubilee in 1887—36 years ago.)

Ed.—EKO AKET

## "OṢUPA NTAN'NA IRAWỌ NTAN."

( Bi *Electric* Ọba ti ntan, bẹni tirẹ yio si ma tan. )





Ẹnik[illegible]i mọ pe yiyara tan Atupa yi ati imọlẹ rẹ ko lẹgbẹ, pataki ohun to mu [illegible]polowo [illegible]inu iwe irohin yi, ni pe, Oyinbo ti nṣe Atupa pataki yi fun Olokiki Saka-Jojo [illegible]a laṣẹ, [illegible]o ma ta wọn ni owo pọ-ọ fun ẹnikẹni, ki gbogbo onibara rẹ to wa ni *Nigeria* [illegible] agbegb[illegible]le ko-ifa ẸDINWO NLANLA ti a ṣe yi.

Wọnyi ni [illegible]ninu ohun to jẹ ki Atupa yi SOYIGI fun gbogbo Atupa ti nwọn nta l'Eko.

1. Ọd[illegible]kinni :—Epo Karosini l'afi ntan.
2. [illegible]keji :—Anfani ti o wa lati ri orişirişi irinşẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.
3. [illegible]Ikẹta :—Ikini lọkan lati ma tun ṣe nigba gbogbo ti o ba bajẹ.

Lọ bẹ[illegible] ni ile ọja rẹ ni opopo gbọkankan ( *Victoria Road* ) ati Idunmagbo.

*Irohin ko to afojuba.*

Phone, L214 — S. FRANCIS LAWANI,

P.O. Box 159. — *alias* Saka-Jojo.



## ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopo nla lẹmẹta lọsẹ.

Awọ-ṣẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan.

Ọrẹ, lọ fi oju ẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday, Wednesday ati Saturday,* ni agogo mẹjọ abọ alẹ ( *8.30 p.m.* )

## "EKUTE !" "IKA !!" (FINGER) "ỌMỌ !!!

Nigbati a ba ti ri ara ẹni pẹ, boya o ni iye ọdun, lẹhin bibere ile ati ọna ara, wa a ma bere pe, "Ọmọde nkọ?" Nigbati awọn ọrẹ wọnyi ba si pade nile ọkan ninu awọn mejeji, ti eyiti o ṣẹṣẹ ti idalẹ de ba si ri ti awọn ọmode nta kọṣọ kọṣọ kọṣọ kiri inu ile, a fi ifẹ bere pe, "tabi awọn ọmọ rẹ ni iwọnyi? Kaka ki ọrẹ ti o bimọ yi wipe awọn ọmọ mi ni a ni "Mo dupẹ lọwọ Ọlọrun, awọn "EKUTE" ti o fun mi ni yẹn o!

2. Bi enia ba ku, ti a ba ndaro, rẹ ọmọ sa jasi ohun ti awa enia dudu gbe ni iankẹ pupọ, a ma bere pe "lagbaja ti o ku ko fi ọmọ silẹ bi o?" Kaka ki nwon sọ pe (iyẹn bi o ba bimọ ni o) "o fi ọmọ silẹ" nwọn a ni "o ni IKA" kan (tabi ju bẹ lọ) nilẹ!!! (Enia ha tilẹ le ku tan botiwu ki o lẹwa to, ki a ke ika rẹ pamọ? Ẹran tan lọja ni?!!)

3. Yala ọkunrin ni tabi obinrin ti o ba jẹ onişina (panṣaga) ti gbogbo enia si ti pe owo rẹ ni, ti iru ẹni bẹ ba darugbo laini ọmọ kan kan, nigbati enia yio ba ma daro rẹ, nwọn a ni, "ye, o ma ṣe o, Ọlọrun iba tilẹ fun lagbaja ni IKA kan! ṣe iba dun!"

On papa le ma sare nipa egbogi ati ajo loniruru ọna, a si ma wipe "nba jẹ ni IKA kan laiye!!"

Niti panṣaga? Ṣe ika mẹwa l'o mu waiye? Ki l' o jẹ mẹsan yoku, ki o to ma tọrọ koro kan nigbati ilẹ ṣu tan? Olugbodi a ma ni ika mejila kẹ!

Bi Yoruba ba sọrọ loju ẹniti o pe on gbọ Yoruba inu iwe jẹki o farabalẹ ki o ma ba fi ijinlẹ ede gbe e ta, ọrọ ori oke ni nsọ nigbati aluigbọ ijinlẹ ede ro pe ọrọ pẹtẹlẹ l'o nsọ. Nigbati o ba gbọ LARINKA tabi EKUTE ati IKA (*Finger*) ni igbọ awo, jẹki o ja ọ ninu pe ọrọ ti nwọn nsọ, ọrọ "ỌMỌ" ni!!!

"MORAWỌ."

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.

£12—£12 10 fun *ton* kan

EPO.

£23—£24 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£25 fun *ton* kan bakanna.

---


## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ijẹbu-Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers :—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*

Readers I to III—3/- *per Quarter.*

Readers IV and V—6/- *per Quarter.*

Classes I to III—9/- *per Qualer.*

Boarding Fee—£1 2s 6d, Monthly.

This is beside the Tuition Fee ; and includes Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services.

PLEASE NOTE

Payments strictly in advance otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYO SORINOLU,
*Principal & Proprietor.*

Iporo Ake, Abẹokuta.


---

## KABỌ, ỌMỌ-ALOSI BI ẸNI OGUN.

A ki ọrẹ wa Stanley Benjamin kabọ lati Ilu Oyinbo nibi ti o ti lọ kọ iṣẹ Loya (*Lawyer.*) Ọgbẹni na ba ọkọ ilinsi de ni *Thursday* ọsẹ yi, o ti di Loya o si bura niwaju Adajọ Agba larọ yi.

**All for Bicycles and Motors.**

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address:*—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.


## IYA AFIN SABINA BỌLAJOKO

Ti No. 39, Ita Matinin jẹ ẹniti o gbaṣẹ ati ma ta orişirişi ỌTI o si nta awọn nkan Ipara ni Ṣabu rẹ yi.

Ẹ lọ ke si i, Wara-ṣeṣa ni ọja rẹ, owo wọn si mọ-ni-wọn ti makunnu.


***The Philharmonic Band.***



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si
*THE SECRETARY,*
c/o Aafani Motors
The Marina Lagos.

"KO-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi işẹ ni lapa şe fuja, bẹrẹ si Işẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aşọ riran ni aşa orişirişi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ işẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

DRESS-MAKING.
"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

"O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aşẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun ẹnia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | Rev. H. W. Stacey |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. D. A. Babatunmi |
| 7 p.m. | | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. N. A. Thompson |
| 7 p.m. | | „ E. E. Ajose |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. M. B. Newton |
| 7 p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. A. M. Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Lalaleye |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A. Akiola |
| 6.30 p.m. | | Rev. N. B. Newton |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. A. T. Fayan |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. Samuel Johnson |
| 4.30 p.m. | | Bro. E. A. Willimas |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. A. T. Openiyi |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

**EBENEZER (BAPTIST)**

Rev. E. C. Alabi
Bro. E. A. Ojo

**BROTHERHOOD**

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. J. A. Domingo |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon; Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

---


W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!!!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu ALAMASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọyọku

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER, Oniṣowo ara Jamani ni Ita 7, Labinjọ, leti Ita William lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun-orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE

Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE

Awo Abọmafọ ENAMELWARES

Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.

Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

Messrs. J. R. Thomas & Sons of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc., etc., to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices. This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back, and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

## WHY LOOKING SAD ?

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous postration or loss of memory why don't you use Mulracithin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthenia etc., etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine, the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills, and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajenifuja" Store No. 109 & 111, Broad Street.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

## WANTED.

Reliable Agents required for sale of English Ready-made COFFINS, at Lagos Abẹokuta, Ibadan and Jebu-Ode.
For Terms and Conditions,
Apply to A. BANK-ANTHONY,
137, Tokunbọ Street, Lagos.

## A TOTO, O!

A nfẹ Enia "GIRIKI" ti yio ṣe oju Ọgbẹni A. BANK ANTHONY ni Eko, Abẹokuta, Ibadan, tabi Ijẹbu-Ode, lati ma a ta awọn POSI-meremere, ti o ti ilu Ọb wa tun Ọgbẹni Onisọwo na.

Ẹniti o ba nfẹ, ki o kọwe si Ọgbẹni na. ni adugbo rẹ 137 Ita Tokunbọ l'Eko.

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## "EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.
Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.
Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

## WANTED.

A good COOK capable of preparing all kinds of Native "Chops."
Good wages to a suitable man.
Apply to the Editor of this Paper.

## PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onisọwo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko-o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nṣe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi ṣile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi oriṣi-riṣi iwosan onirunru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan mere-mere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku-yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati ṣi ile Ẹrọ Idan Awoṣẹju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Ṣoroko a gbe ṣẹranwo ni igbati o ba ṣi ibẹ Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 21*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASE
106, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams.*—Alawọbata, Eko.


## ỌBẸ L' ỌMU AGBA

A nfẹ "Kúkù" to mọ orișirișI Onjẹ Ilẹ wa ni sise. To si le jẹ ki ọbẹ ma sọ "Tapa" lori ina. To si mọ "Kọtọ" Ọbẹ di lọwọkan.

A o sanwo Oșu to rọju fun ẹniti o ba mọ ișẹ yi șe.

E kọwe si Oniwe Irohin yi.


## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUY

Fun Ile Ẹko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sà kan nitori ogun Germani, șugbọn won tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kișe ișẹ *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.



## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA.!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD
8, Tinubu Square, Lagos.

Ki la ti nș' oku l' ọrun?
Ki la ti nș' ori mle Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa șa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.